**ORÍ ÒKÈ INÁ ÀTI IṢẸ́ ÌYANU**

Olú Ilé Iṣẹ́ Ìránṣẹ́, Ìpínlẹ̀ Èkó, Nigeria.

**ÈTÒ ÌPÀDÉ AGBÁRA GBỌ́DỌ̀ PÀRỌ̀ ỌWỌ́**

**BÍBORÍ ÌWÀ ÌKÀ ÌDÍLÉ (2)**

**OṢÙ KẸRIN, ỌDÚN 2025**

Ìwé Mímọ́ Kíkà: Gẹ́nẹ́sísí 4

Ìjẹ́wọ́: Lúkù 10:19

## ORIN ÌYÌN ÀTI ÌJỌ́SÌN TÍ Ó L'ÁGBÁRA

1. Ọlọ́run, dìde, kí Ó sì fàtu ohunkóhun tí O kò gbìn sínú Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
2. Ọlọ́run, jẹ́ kí iná ìṣọ́ji, bà lé Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
3. Ọlọ́run, jẹ́ kí agbára àláfíà àti itẹ̀síwájú, ṣíji bo orílẹ̀-èdè yìí, ní orúkọ Jésù.
4. Ọlọ́run, dìde, kí O sì fún wa ní àwọn olórí tó bẹ̀rù Ọlọ́run, ní orúkọ Jésù.
5. Iná àjonirun Ọlọ́run, jo gbogbo àmì ìpọ́njú nínú ayé mi run, ní orúkọ Jésù.
6. Gbogbo ìyàbàrà àti ìparun lórí ayé àti ayànmọ́ mi, jó di éérú, ní orúkọ Jésù.
7. Ìwà-ìkà ìdílé bàbá mi, tó n ṣiṣẹ́ pọ̀ pẹ̀lú àwọn agbára agbègbè lòdì sí ayé mi, túká, ní orúkọ Jésù.
8. Gbogbo ìjókò ìwà-ìkà nínú ìdílé mi, yangbẹ nípa iná Ọlọ́run, ní orúkọ Jésù.
9. Gbogbo ètò ìkà ìdílé tí wọ́n yàn láti mú ìjákulẹ̀ bá ayé mi, gba itìjú, ní orúkọ Jésù.
10. Olúwa, ṣí gbogbo ilẹ̀kùn rere ayé mi tí ìwà-ìkà ìdílé ti tìpa, ní orúkọ Jésù.

11. Ìpọ́njú ẹ̀jẹ̀ ìran, tó n yọ ayé àti ayànmọ́ mi lẹ́nu, sọ agbára rẹ nù lórí mi, ní orúkọ Jésù.
12. Ègún ẹ̀jẹ̀ ìran, túmisílẹ̀ nípa agbára tó mbẹ nínú ẹ̀jẹ̀ Jésù, ní orúkọ Jésù.
13. Ìrúnú ẹ̀jẹ̀ ìran, tó nmú idàrúdàpọ̀ bá ayànmọ́ mi, gba ìpalẹ́numọ́ nípa agbára tó mbẹ nínú ẹ̀jẹ̀ Jésù, ní orúkọ Jésù.
14. Olúwa, gẹ́gẹ́ bí O ṣe jókò ní ọ̀run, fi àwọn ọ̀tá mi rẹ́rìn, ní orúkọ Jésù.
15. Ẹ̀yin ọ̀tá mi tó n dígbọ́n láti daṣọ bò mí ṣùgbọ́n tí wọ́n n tú ìhòhò mi síta, ẹ̀san láti ọ̀run, yà wọ́n lárọ, ní orúkọ Jésù.
16. Olúwa, rán àwọn ángẹ́lì Rẹ láti yí ìtẹ́ ayànmọ́ mi ká lòdì sí àwọn ọ̀tá mi, ní orúkọ Jésù.
17. Kinìún ẹ̀yà Júdà, bú ramúramù láti fa àwọn ọ̀tá mi ya pẹ́rẹpẹ̀rẹ, ní orúkọ Jésù.
18. Àwọn ọ̀tá mi kòní bọ́ kúrò nínú gbogbo pámpẹ́ tí wọ́n dẹ fún mi, ní orúkọ Jésù.
19. Olúwa, já ẹ̀rín mi gbà kúrò lọ́wọ́ gbogbo agbára òkùnkùn, ní orúkọ Jésù.
20. Àwọn ẹ̀mí òkùnkùn àìmọ́ tí wọ́n n dígbọ́n gẹ́gẹ́ bí èmi láti jí àwọn ibùkún mi, kí àṣírí wọn tú, kí wọ́n sì gba ìparun, ní orúkọ Jésù.
21. Àwọn ẹ̀mí òkùnkùn aìmọ́, tí wọ́n ti jẹ́ẹ̀jẹ́ láti jẹ́ ìdènà nlá lòdì sí mi, ẹ wólulẹ̀, kí ẹ sì jórun nípa iná, ní orúkọ Jésù.
22. Ìfijì búburú ìyówù, tí wọ́n yàn láti f'ogun ja ayé mi, kú, ní orúkọ Jésù.
23. Àwọn ìránṣẹ́ òkùnkùn tí wọ́n fi ara wọn jì láti rí òpin mi, ẹ gba ìparun láìláánú, ní orúkọ Jésù.
24. Àwọn agbára tí wọ́n ti mú ọjọ́ láti pamilẹ́kún, Olúwa, fi wọ́n ṣòfò, ní orúkọ Jésù.
25. Olúwa, ká àánú Rẹ kúrò lọ́dọ̀ àwọn ọ̀tá mi, ní orúkọ Jésù.
26. Olúwa, tú ìtọrẹ-àánú tí àwọn ọ̀tá mi nṣé e lòdì sí mi ká, ní orúkọ Jésù.
27. Àmì aṣìṣe nlá, wá sórí àwọn ọ̀tá mi, ní orúkọ Jésù.

28. Agbára òkùnkùn ìyówù, tóti dúkokò láti gbógun tì mí dójú ikú, Olúwa, pa á ní kíákíá, ní orúkọ Jésù.
29. Gbogbo agbára òkùnkùn tó n rúbọ sí mi láti kú, Olúwa, fi wọ́n ṣòfò, ní orúkọ Jésù.
30. Èmi kòní kú láti ọwọ́ òmìrán ìdílé mi, ní orúkọ Jésù.
31. Olúwa, pa abọ̀dè-kí-abọ̀dè láyiká mi, ní orúkọ Jésù.
32. Olúwa, ṣí ilẹ̀kùn rere tí mi ò tí wọnú rẹ̀ rí, ní orúkọ Jésù.
33. Olúwa, jẹ́ kí n gbádùn májẹ̀mú ibùkún Rẹ, ní orúkọ Jésù.
34. Gbogbo ọwọ́ tó n ba iṣẹ́ ọwọ́ mi jẹ́, jórun nípa iná, ní orúkọ Jésù.
35. Olúwa, fihan gbogbo ayé wí pé iṣòro mi lè yanjú, ní orúkọ Jésù.
36. Gbogbo ibi giga òkùnkùn tó n dìde lòdì sí mi, wọlẹ̀ nípa iná, ní orúkọ Jésù.
37. Iná ìparun látọ̀run, pa àwọn ọ̀tá mi run tìtí dé gbòngbò wọn, ní orúkọ Jésù.
38. Ohunkóhun tí àwọn agbára òkùnkùn nlò láti ṣe alamí lòdì sí mi, jórun nípa iná, ní orúkọ Jésù.
39. Amí òkùnkùn, ṣe aṣìṣe tí yóò jó ìwọ àti àwọn tí ó rán ọ run, ní orúkọ Jésù.
40. Ọlọ́run, dìde, jẹ́ kí ndi ẹni-nlá, ní orúkọ Jésù.